# IPỌNJU WA TI O FẸRẸ̀

**2 Kọrinti 4:17, 18; 5:1-10**

**ẸKỌ 396 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Ipọnju wa ti o fẹrẹ, ti iṣe fun iṣẹju kan, o nṣiṣẹ ogo ainipẹkun ti o pọ̀ rekọja fun wa" (2 Kọrinti 4:17).**

**I Awọn Ipọnju Olododo**

1 Jijiya fun Kristi n ṣiṣẹ sipa ogún ti o logo ju lọ, 2 Kọrinti 4:17; 2 Timoteu 2:12; Heberu 12:11

2 Oju ti Ẹmi maa n fi bi awọn ohun ti ayeraye ti niyelori to hàn, 2 Kọrinti 4:18; Orin Dafidi 102:25, 26; Ifihan 21:1

**II Ireti Ọrun**

1 Ọlọrun ni àye kan ti o ti pese silẹ fun awọn ẹni irapada Rẹ̀, 2 Kọrinti 5:1; Johannu 14:2, 3

2 Ifẹ ti o jinlẹ fun Ọrun wà ninu ọkan awọn Onigbagbọ tootọ, 2 Kọrinti 5:2-4, 6-8; Filippi 1:23

3 Ẹmi ṣe ileri iye ainipẹkun fun awọn oloootọ, 2 Kọrinti 5:5; 1 Peteru 1:4, 5

4 Gbogbo eniyan kò le ṣai ma fara hàn niwaju itẹ idajọ Kristi, 2 Kọrinti 5:9, 10; Romu 14:10

## ALAYE

Ni ọdun diẹ sẹyin, ọpọ eniyan n ṣiṣẹ ninu ọgba iko-mọto jọ si, wọn si n du u lati yọ ikoko idi mọto kuro lara mọto kan. Pẹlu gbogbo igbiyanju wọn ati oriṣiriṣi ọgbọn ti wọn lo, n ṣe ni ikoko idi mọto yi duro gbọnin. Nigbooṣe ọga awọn atun-mọto-ṣe naa wi pe, "Ẹ dá iná ki a si fi idi rẹ ra ina wo." Laarin iṣẹju kan si meji ti wọn fi idi rẹ ra ina, lọgan ni wọn yọ ikoko idi mọto naa jade pẹlu irọrun.

N jẹ eyi yi kò ha n ba ni sọ iru ọna kan naa ti Ọlọrun maa n saba gba fi ba eniyan lo? O maa n gba Ọlọrun ni oniruuru ọna lati rọ̀ awọn eniyan ki wọn tẹ̀ si ifẹ ti Rẹ̀, ṣugbọn ni igba gbogbo ni wọn maa n kuna lati kọbi ara sii. Nikẹyin, Oluwa a si gba pe ki a lo ina (ni ọna pupọ nipa ina ti ipọnju); nigba naa ọkàn a si jọgọ silẹ kiakia.

### Ogo ti O Pọ̀ Rekọja

Iwe Mimọ sọ pe ipọnju "nṣiṣẹ ogo ainipẹkun ti o pọ̀ rekọja fun wa." Nihin, Ẹmi n sọ nipa ipọnju wọnni ti o n fa eniyan sunmọ Ọlọrun. Awọn eniyan buburu paapaa a maa ni ipọnju; ṣugbọn ninu ipọnju naa, bi wọn ko ba yipada si Ọlọrun, iya ti wọn jẹ ki yoo jẹ ere kankan fun wọn. Inunibini, idojukọ, irẹsilẹ, owusuwusu oye ori, irẹwẹsi, ijatilẹ, ibanujẹ, arokan: gbogbo wọnyii wà lara awọn ipọnju ti a le mu ki ẹnikẹni là kọja nigba miiran.

Bi eniyan ba gba ipọnju laaye lati mu oun wá sinu ifẹ Ọlọrun, nigba naa eniyan yoo mọ bi iye-ainipẹkun ti niyelori to. Ni tootọ ipọnju ti o fẹrẹ ni bi a ba fi ṣe akawe ogo ayeraye ti o pọ̀ rekọja. Ipọnju fẹ́rẹ̀, bẹẹ ni ogo rẹ "ainipẹkun si pọ̀ rekọja," nitori pe akoko gẹgẹ bi iṣiro ọdun ninu aye yii n yara lọ, ṣugbọn ayeraye wà titi lae.

Chrysostom, alufaa pataki ti o wà ninu aye ni nnkan bi irinwo ọdun lẹyin ti a bi Jesu, ṣe akiyesi ọrọ wọnyi: "Apọsteli naa dojuja kọ awọn nnkan igba isisiyii nitori ti eyi ti n bọ; o fi iṣẹju kan wé ayeraye; o fi ohun ti o fẹrẹ wé eyi ti o wúwo; o fi ipọnju wé ògo. Ṣugbọn gbolohun yii ko tẹ ẹ lọrun to, o tun fi ọrọ miiran kun un, bi a ba si fi oju inu wo o, o ni oorìn ilọpo meji, ni ti bayii pe 'O papọju rekọja aalà' ".

### Iriran ti Ẹmi

Bibeli n tọka si i lati igba de igba bi o ti jẹ iwa were to lati maa gbe awọn nnkan wọnni ti a n ri (ohun igba diẹ) si ipo giga ju lọ ni igbesi-aye ẹni. Awọn nnkan wọnni ti a ko le fi oju ti a fi n riran yii ri (awọn ohun ayeraye) ni nikan ti o niyelori ju lọ. Igba ti eniyan ba n wo aye yii gẹgẹ bi atẹgun lọ si Ọrun, ori ilẹ aye yii gẹgẹ bi yara iwọṣọ fun Ile-Ogo, ni ẹni naa yoo to ni ayọ pe oju oun riran kedere. Awọn Onigbagbọ́ aṣẹgun ti inu Bibeli maa n fi ọwọ yẹpẹrẹ di awọn nnkan aye mú, ṣugbọn ohun ti wọn

maa n fi ṣe pataki ju lọ ni ohunkohun ti wọn le sọ tabi ti wọn le ṣe nipa ti ọran ajinde ologo. A woye pe awọn Onigbagbọ aṣẹgun lọjọ oni ko gbọdọ ṣe dinku si eyi nì.

Bawo, nigba naa, ni eniyan ṣe le maa wo "ohun ti a kò ri"? Nipa fifi oju igbagbọ wo Oluwa Jesu Kristi. Ki Ọgbẹni Columbus to rin irin-ajo rẹ̀ ti a ṣe akọsilẹ rẹ̀ ninu iwe itan ninu eyi ti o ṣe awari Orilẹ-ede titun, awọn eniyan ti maa n jiyan nipa ohun ti o wà ni okeere rére ni odikeji agbami okun. Bakan naa ni eyi jẹ́ otitọ, ni apakan nipa ti iye ainipẹkun. Jesu Kristi ni Ẹni ti O la ọna silẹ. Ki O to wá si aye, ki O to ku ki O si to ni iṣẹgun ninu ajinde Rẹ̀, ayeraye ti jẹ nnkan kayefi ninu ọkàn ọpọlọpọ eniyan. Lotitọ, ṣiwaju Kristi paapaa ni ẹri ti maa n dún lẹnu awọn eniyan Ọlọrun miiran ni ti igbagbọ ati ireti ti wọn ni ninu iye ainipẹkun; ṣugbọn nigba ti Jesu de, Oun gan an wá jẹ apẹẹrẹ ojukoju fun iru idaniloju bẹẹ. Nipa wiwo Jesu Olupilẹṣẹ ati Alaṣepe igbagbọ wa, a le maa wo ọna fun iye ainipẹkun pẹlu igboya, ki a si mọ pe Ọlọrun ti ṣe ipese kikun silẹ fun wiwa ni alaafia awọn ẹni-irapada ni ayeraye. "Olubukún li Ọlọrun ati Baba Jesu Kristi Oluwa wa, Ẹniti o tún wa bi, gẹgẹ bi ọ̀pọlọpọ ãnu rẹ̀, sinu ireti ãye nipa ajinde Jesu Kristi kuro ninu oku, sinu ogún aidibajẹ, ati ailabawọn, ati eyi ti ki iṣá, ti a ti fi pamọ́ li ọrun dè nyin" (1 Peteru 1:3, 4).

**Imọ ti O Daju**

"Nitori awa mọ̀ pe, bi ile agọ́ wa ti aiye bá wó, awa ni ile kan lati ọdọ Ọlọrun, ile ti a kò fi ọwọ́ kọ́, ti aiyeraiye ninu awọn ọrun." Ẹsẹ yii n sọ gbangba nipa ikú ti ara, ṣugbọn kò si ami ẹ̀dun tabi ibanujẹ kan rara. Dipo eyi, a gbọ́ ohùn ati ìro ifojusọna ti o ni ireti, ki ni ṣe ti ki yoo si fi ri bẹẹ?

Nigba ti ile ninu aye yii ba di ogbologbo ti o si fẹrẹ wo lulẹ, o n fẹ ki a tun un kọ́. Onile a si le awọn olugbe inu rẹ jade, nigba naa a wo ile naa palẹ, a si kọ́ ile titun ti o si lagbara ju ogbologbo nì lọ. Eyi ki i mu ki awọn olugbe ile naa banujẹ, ṣugbọn wọn a kún fun ayọ. Wọn ki i ronu rara nipa wiwo ogbologbo ile naa lulẹ, nitori pe wọn n fi oju sọna fun ile titun ti a o fi rọpo rẹ̀.

Aworan yii gan an ni Ẹmi n ṣe apejuwe ninu ẹkọ yii. Iru iṣẹ kan naa ni Ọlọrun n ṣe nigba ti ọmọ Rẹ̀ kan ba fi aye yii silẹ. Ẹmi eniyan tabi ọkàn yoo pada si ọdọ Ọlọrun ti o fifun ni. Ile ti ayé, tabi agọ́ ara yoo di wiwó, a si pada di erupẹ ninu eyi ti a ti mu un jade wá. Ni akoko ti Ọlọrun, a o ji ara naa dide lati inu erupẹ, a o si sọ ọ di ara aidibajẹ. Ẹmi ati ara ologo naa yoo tun papọ lọjọ naa, "lati wa lae lọdọ Oluwa" (1 Kọrinti 15:51-54). Ironu bibọ́ agọ erupọ silẹ kò le daya fo Onigbagbọ tootọ, nitori o mọ pe ibugbe ti o dara ju eyi lọ n duro de oun.

Ni idakeji ẹwẹ, gẹgẹ bi o ti ri ninu ori Iwe Mimọ yii, ifojusọna wà fun ohun iṣẹlẹ naa. Apọsteli naa wi pe: "Emi mbẹ ni iye-meji, mo ni ifẹ lati lọ ati lati wà lọdọ Kristi; nitori o dara pupọ ju: sibẹ lati wà ninu ara jẹ anfani nitori ti nyin" (Filippi 1:23, 24). Ọ̀kan ninu awọn alufaa ti ipilẹ Ijọ Igbagbọ Apọsteli, nigba ti ẹni kan ti n ṣe itọju rẹ̀ bi i leere ohun ti oun i ba ṣe fun un lati mu irora rẹ̀ dinku, o ni: "Ṣí orule yii kuro ki n le kọja lọ." Igbagbọ rẹ̀ duro ṣinṣin, o si daju. Ni iṣẹju diẹ si i, o dakẹ, o si kọja lọ lati wà pẹlu Oluwa.

**"Nkan Kan naa"**

"Ẹniti o ṣe wa fun nkan yi ni Ọlọrun" – ni aiṣe ani-ani, eyi n tọka si gbolohun ọrọ ti o wà ṣiwaju rẹ̀ timọtimọ; "ki iyè ki o le gbé ara kiku mì." Ẹmi n kọ́ ni pe Ọlọrun ni ọwọ́ ninu iṣakoso igbesi-ayé awọn eniyan Rẹ̀. Igbesi-ayé Onigbagbọ tootọ ki i ṣe omi adagun ti n pooyi lasan, bẹẹ ni ki i ṣe eyi ti o kún fun oriṣiriṣi iṣẹlẹ ti o ṣeeṣi ri bẹẹ. Agbara kan wà ti o n ti igbesi-ayé olukuluku ọmọ Ọlọrun lẹyin – Agbara ti n sun ni mọ́ ebute Ọ̀run.

Ẹmi Ọlọrun n ṣiṣẹ ninu gbogbo ọkàn ti wọn ba jọwọ ara wọn fun Un lati pese wọn silẹ fun Ọrun. Lotitọ, olukuluku ẹni ti a gbala ni itara ninu ọkan rẹ̀ fun iye ainipẹkun, ṣugbọn afo ṣi silẹ fun idagbasoke nipa ti ẹmi ati lati lọ si pipé. Oniwe akọsilẹ kan ṣe alaye daradara kan lori ero yii pe: "Gbogbo ẹ̀kọ́ ti a n fi suuru kọ́ ninu ibanujẹ ati inudidun, ninu isọji ti o n fun ọkàn wa layọ ati iṣudẹdẹ ti o n mú ọkàn wa rẹwẹsi, ninu imọlẹ ti o n mu ọkàn yọ̀ ati ninu okunkun ti o n mu ibanujẹ bá ọkàn ati ki oju faro, gbogbo iwọnyi ni o n mu ni lọ sinu igbesi-ayé pipe ti i ṣe ti ọkàn pipe, ti o si le sọ ara paapaa di pipe lati wà ni ibugbe ibiti kò gbé si ohun aimọ́." Ọrun yoo jẹ́ ère kikun fun gbogbo laalaa ti a ṣe.

**Itẹ́ Idajọ**

Nitori naa, o jẹ iṣẹ Onigbagbọ ninu ayé yii, lati ṣe ohun ti o wu Kristi ati lati wà ni imurasilẹ fun Ọrun. Ṣiṣe iṣẹ yii si ni mimu ọkàn ati iwa aye wa bá Ọrọ Ọlọrun dọgba, ki a si maa làkaka ni gbogbo ọ̀na lati mu ki Ihinrere tankalẹ de ọdọ gbogbo eniyan lori ilẹ ayé. Iye awọn wọnni ti o ba mu ifẹ Kristi ṣẹ bayii ni yoo jẹ́ ẹni itẹwọgba lọdọ Rẹ̀.

Awọn wọnni ti wọn si kọ̀ lati ṣe ifẹ Ọlọrun ni lati wá si idajọ fun kikọ̀ ti wọn kọ̀ ati nitori iṣẹ buburu won. "O ti da ọjọ kan, ninu eyi ti yio ṣe idajọ aiye li ododo, nipasẹ ọkunrin na ti o ti yàn, nigbati o ti fi ohun idaniloju fun gbogbo enia, niti o ji i dide kuro ninu okú." (Iṣe Awọn Apọsteli 17:31). Sibẹ, "Ẹ̀ṣẹ awọn ẹlomiran a mã han gbangba, a mã lọ ṣaju si idajọ; ti awọn ẹlomiran pẹlu a si mã tẹle wọn" (1 Timoteu 5:24). "Bi awa ba jẹwọ ẹ̀ṣẹ wa, olõtọ ati olododo li on lati dari ẹṣẹ wa ji wa, ati lati wẹ̀ wa nù kuro ninu aiṣododo gbogbo" (1 Johannu 1:9).

Awọn wọnni ti a kọ orukọ wọn sinu Iwe Iye Ọdọ-agutan kò tun ni bẹru idajọ mọ́ nitori wọn ti dá ara wọn lẹjọ nipa Ọrọ Ọlọrun. (Wo 1 Kọrinti 11:31). Eyi si ni pe, wọn ti fara mọ́ Ọrọ Ọlọrun, wọn ti ronupiwada awọn ẹ̀ṣẹ wọn, wọn ti gba Ọmọ Ọlọrun gbọ́ gẹgẹ bi Olugbala wọn. A si ti wẹ awọn ẹ̀ṣẹ wọn nù ninu Ẹjẹ Ẹni naa ti a kàn mọ́gi. Bi wọn ba duro ninu oore-ọfẹ yii, wọn yoo le dahun pe, "Bẹẹni" si ọrọ orin yi:

**"O ha ṣe tan? O ha ṣe tan?**

**O ṣetan fun Ọjọ Idajọ?"**

## AWỌN IBEERE

1 Ọna wo ni Onigbagbọ le gba sọ pe, "Ipọnju wa ti o fẹrẹ, ti iṣe fun iṣẹ́ju kan"?

2 Iru iṣẹ wo ni ipọnju n ṣe ninu igbesi-ayé ọmọ Ọlọrun, bi a ba fi ọkàn ti o tọ́ gbà á?

3 Bawo ni a ṣe le wo awọn "ohun airi"?

4 Ọna wo ni Ọlọrun fi ṣe ipese silẹ fun awọn ọmọ Rẹ̀ nigba ti wọn bá fi ayé yii silẹ?

5 Sọ ọ̀kan ninu ọ̀pọlọpọ ẹsẹ Iwe Mimọ ti o fi hàn pe nigba miiran ongbẹ Ọrun maa n gbẹ awọn Onigbagbọ́.

6 Ki ni yẹ ki o jẹ́ opin ti Onigbagbọ́ n lepa ninu laalaa rẹ̀?

7 Ki ni ṣe ti ọmọ Ọlọrun kò fi gbọdọ bẹru itẹ idajọ Kristi?

8 Ki ni ẹlẹṣẹ yoo dahun fún ni Ọjọ Idajọ?